**Owe**

Ina ti Ikoko Saws o ngba kurukuru S'omi.
Abinuẹni ko ri koto tirẹ si. Ohun ti Ọlọrun yio ṣe ko ti han Ẹnikan.

# ÌROHIN ÌMỌLẸ

MOTTO: IMỌLẸ DE, OKUNKUN PARADA.

**Wanted**

Experienced Ladies advertisement Canvassers Apply personally Advertisement Manager Irohin Imole.
16, Bamgbose Street, Lagos.

VOL. VI No. 340 MONDAY JULY 30 — AUGUST 5 1962 KỌBỌ MEJI (2d)


# SANGBAFỌ, AKARA AKINTỌLA TU S'EPO

IBADAN:— Awọn Ọlọpa mu awọn Ọdaran mẹsan kan, Gabriel Oluwo, Salami Makinde, Afọlabi Oluwo, Ayẹni Dada, Adeniyi Akintọla, Gabriel Adenloye, Jacob Ọlawuyi, ati Iyaafin Arinmọ e Iyadun, wa siwaju Oloye Adedapọ Aderẹmi Adajọ agba ile ẹjọ kekere Ibadan fun ẹsun pe nwọn nja ni ode gbangba.

Alaye ti Iyaafin Abẹni ọmọaiye ti o ba awọn mẹjọ iyoku ja ṣe niwaju Adajọ ni wipe, on ko ja lasan, Oloye S. L. Akintọla fun Ẹgbẹ Ologboni Ibadan ni ẹdẹgbẹrin pọnun (£700) pe ki gbogbo awọn le ba on si sọ wipe pọnun mẹrin kere ki nwọn fun on si i, nwọn kọ jalẹ pe iye ti awọn yio fun on ni yẹn ni awọn ba bẹrẹsi ija, ti awọn si ngna ara awọn ni anaja lokun sokoto. Ni awọn Ọlapa ba fi ko awọn wa si



OLOYE S. L. AKINTỌLA OLORI ẸGBẸ U. P. P.

dibo fun un ninu ibo ti o mbọ yi. Iyaafin ọmọaiye sọ wipe ọkan pataki ninu awọn ọmọ Ẹgbẹ na ni on, nigbati nwọn si pin owo na (£700) nwọn fun on ni pọnun mẹrin (£4). Nigbati kotu. Obinrin na sọ wipe owo ti on ko gbọdọ jẹ pọnun mẹrin rara.

Adajọ ni ki nwọn o maa lọ ni alafia, ṣugbọn nwọn ko gbọdọ ja mọ fun oṣu mẹsan.

## Ẹnkuari Coker bẹrẹ l'Eko

Iwadi ti Apapọ Ijọba Naijiria yan lati ṣe iwadi bi Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ti a ti da duro lẹnu iṣẹ bẹrẹ iṣẹ wọn l'Eko.

Nigbati Oloye Obafẹmi Awolọwọ wọle ni ọjọ na o ri Oloye Akintọla o si gbau lọwọ o ni "Ẹ nlọ o, ṣe alafia ni?" olukuluku si joko.

Ki awọn Oluwadi na to bẹrẹ ni Alaga Iwadi na Adajọ agba G. B. A. Coker ṣe kilọkilọ fun awọn Oniwe Irohin pe ki awọn o maa kọ irohin wọn bi nkan ti nlọ si ati ohun ti awọn nṣe. Ti awọn ba ri iwe Irohin ti o ba ṣe irohin ti ko dara awọn yio muu gẹgẹbi arufin.

Bi iwadi na ba ti nlọ ẹo ma gbọ o.

## Ijọba fi ofin Pajawiri gbe awọn Oniwe Irohin meji !

EKO:— Dọkita M. A. Majẹkodunmi Alamojuto Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria, ti fi ofin pajawiri gbe awọn Ọga Oniwe Irohin meji Ọgbẹni L. K. Jakande ati Ọgbẹni Bisi Ọnabanjọ kuro ni Eko ni ọjọ Ru ti iṣe ọjọ kẹdọgbọn oṣu yi.

Ijọba ko sọ idi rẹ ti a fi gbe awọn mejeji yi kuro l'Eko.

Ọgbẹni Jakande ko gbọdọ kọja idaji ibusọ si ilu Burutu ati Ọgbẹni Bisi Ọnabanjọ ko gbọdọ kọja ibusọ kan bakanna ni Forcados. Awọn ilu mejeji yi wa ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria.

Ki awọn Ọlọpa to mu Ọgbẹni Bisi Ọnabanjọ kuro l'Eko ni Ọgbẹni na sọ wipe nigbati Dọkita Majẹkodunmi de Ibadan o sọ fun gbogbo enia ipinlẹ na wipe, ofin pajawiri ti o wa ni Ipinlẹ na wa fun awọn Oselu ti edeaiyede wa larin wọn ki ija ma ba ṣe wa larin enia Ipinlẹ na. Ṣugbọn ko si ija larin enikankan Alamojuto na si tun nfi ofin pajawiri dẹruba awọn enia.



LATEEF JAKANNDE
"JOHN WEST"

Ọgbẹni Ọnabanjọ sọ pe, on lero wipe ẹru mba Majẹkodunmi nitoripe on fẹ ṣe iwadi awọn Ijọba gbogbo ti Majẹkodunmi jẹ ọkan ninu wọn

Ọnabanjọ tun sọ wipe, Dọkita Majẹkodunmi njaya nitoripe gbogbo awọn enia Naijiria ni yio mọ asiri ti o wa larin Majẹkodunmi ati Apapọ Ijọba Naijiria, nipa



BISI ONABANJO
"AIYEKOTỌ"

ile rẹ ti wọn npe ni (Lion Building) ti Majẹkodunmi ta fun Ijọba ti o si jẹ ere £159,000 larin ọdun meji nigbati o jẹ wipe (£45,000) ni o fi kọ ile na.

Ọgbẹni Bisi Ọnabanjọ sọ wipe on yio tun kọ ọpọlọpọ nkan jade fun gbogbo enia lati gbọ. Ofin Pajawiri kan ko si le di on lọwọ pẹlu. O si ti awọn Oniwe Irohin ko ba si tẹ ẹ awọn irohin na jade fun gbogbo aiye gbọ on yio tẹ ẹ sinu iwe pẹnpẹn-pẹnpẹn ti on yio si pin kakiri orilẹ ede yi lọfẹ.

# ỌRỌ OLOTU

## Kini Igbẹkẹle Awọn Agabagebe ?

Ọpọlọpọ awọn enia ni o wa ti nwọn nma a nsọ ọrọ, ti nwọn kò si mọ itumọ ohun ti nwọn nsọ jade, bẹni ọpọlọpọ si tun ma nhu iwa kan ti nwọn kò si mọ iru ikan ti iwa na jẹ. Iru awọn enia bẹẹ ni a npe ni Ope enia.

Ṣugbọn ọlọgbọn arekereke ti nwọn mọ pe ki a ma a sọrọ daradara ati ki a ma a huwa daradara ni iyi ọmọ Luwabi ti nwọn ni ọgbọn ẹtan lati fi wasu fun gbogbo enia ti awọn paapa kò si jẹ tele ohun ti nwọn nwi, awọn eni bẹẹ ni a npe ni Agabagebe enia.

Ireti ati igbẹkẹle awọn agabagebe Ọlọgbọn ẹtan yi ni lati ni iyi loju enia ati ki gbogbo enia le mọ wọn ni ẹni-Ọla ati ẹni-Owọ. Ṣugbọn asẹhinwa asẹhinbọ nigbati asiri wọn ba tu, itiju na a wa wuwo lara wọn ju iyi ti nwọn nreti lọ.

Igbẹkẹle agabagebe ni omulẹmofo, iru awọn enia bẹ wa ninu awọn ti nwọn npe ara wọn ni Ojiṣẹ Ọlọrun ti enikeni si mọ pe Ojiṣẹ-Eṣu ni wọn, apanijẹ Ikoriko ti o da aṣọ Aguntan bora niwọn.

Bẹni awọn agabagebe wọnyi wa ninu awọn oselu wa ti ao si ma a wo wọn bi aṣiwaju, ṣugbọn nigbati asiri iwa ibajẹ wọn ba tu sode nan fun gbogbo aiye gbọ, gbogbo igbẹkẹle wọn a wa di asan ati omulemofo.

Eyi ni o mu ki Jesu Kristi fi ma a fi iru awọn enia bẹẹ gegun pe, "Egbe ni fun awọn agabagebe" nitorina ki gbogbo awọn ẹniti o ba nfẹ iyi, Ọla, Eye ati ki a maa pe wọn ni ọmọluwabi maṣe ni igbẹkẹle ninu ki a ma a sọro rere, ki a si ma a hu iwa buburu nitoripe igbẹkẹle agabagebe asan ati omulemofo ni.

Eniti o ba ni eti lati fi gbọ ki o gbọ.

## Alaga Onisowo U. A. C. lọ fun isimi diẹ

Ọgbẹni J. R. Davies. O. B. E. eniti nṣe Alaga awọn ọgbẹ onisowo U. A. C. ni ilẹ Nigeria lọ fun isimi ni ọjọ kokandilogun oṣu July 1962. Ọgbẹni Davies yio lo apa kan ninu isimi rẹ pẹlu iyawo rẹ ni ilu Canada, lẹhin igba ti o ba tẹle ninu rẹ ni ilu oyinbo. Yio wa ni isimi fun nkan bi oṣu meji. Ni akoko yi, Ọgbẹni F. S. Pardoe, eniti nṣe alakoso iṣẹ onisowo U. A. C. ni ila-orun Naijiria ni yio ṣe adele fun.

## ỌMỌ TITUN ALEJO AIYE

Irohin ko to afọputa ni ti Ikomọ jade Ọgbẹni Kẹhinde Thomas ati Iyawo rẹ Ọlayẹmi ti Ọlọrun fi ọmọ Ọkunrin meji ta wọn lọrẹ ni ọjọ kẹtadin logun oṣu kefa ọdun yi ni Nọmba 33, Balogun Street8, homolu.

Nigbati o ti ku ojọ mẹrin ni awọn ero ti beresi de lati Agbowa, Imọte, Orugbo, Ikosi, Eko ati bẹbẹ lọ.

Nigbati ọjọ Ọmọ kiko pe awọn Ọmọ Ijọ Baptist Church ti nse ijọ Baba ọmọ na nio ṣe isin Isọmọ loruko wọn si sọ oruko awọn ọmọ na ni Kehinde Adegbola Thomas ati Taiwo Adegbuyi Thomas Nigbati awọn sọ awọn ọmọ na loruko tan. Baba ọmọ na gbe Burẹdi pẹlu Ọbẹ Ẹja ati Tii fun gbogbo enia ki awọn fi yọnunu.

Ni dede agogo mẹrin irọlẹ ni ẹsẹ gbogbo enia ti pe saauiusanmu. Orisirisi onjẹ adidun oti, ẹmu, ogurọ sitaotu, sige, ati iresi ni baba ọmọ na fi tẹ gbogbo awọn alabaseyẹ ọjọ na lọrun.

Nigbati gbogbo enia ti jẹun tan, ti awọn si ti jo ikan tara, ni awọn Onilu FEDERAL BOYS' ORCHESTRA wa fi ilu wọn si, gbogbo enia wa beresi jo yi gbogbo ilu Shomolu po bi kokoro, ilẹ si nrọ kẹke fun inawo ọjọ na. Faji ọjọ na bua a ya o le gongo. Diẹ ninu awọn enia jankanjankan ti o wa nibi isọmọlọruko na ni wọnyi:- C. A. AKINPELU. SABAINA AMOLE. DORCAS DUROWOJU. EASTER ADEWUYI KEHINDE THOMAS. OLAYEMI THOMAS, Y. A. THOMAS. ADEYEMI THOMAS ADEWALE THOMAS. ADEYINKA THOMAS.

ati awọn miran ti aye kosi lati daruko wọn

Ọlọrun yio wo Ọmọ na o

## YẸYẸNATU! ONI YẸYẸ Eko

Olotu:— Ha! ha! Yẹyẹnatu o ma ku fẹfẹriti Eko yi.

Yẹyẹnatu:— Ẹnyin na ku ilabẹ Eko.

Olotu:— Obẹ wo ni a nla, o si ti ri ole to nji ọbẹ la ni yẹn.

Yẹyẹnatu:— Ha! ha! ha! aiya nyin ti nja ni yẹn ni, gbogbo ẹsẹ ole o dinu tubu.

Olotu:— Yẹs kẹ, ṣe iyẹn ẹsẹ ole

Yẹyẹnatu:— Boya ẹ ko tilẹ mọ ibiti nie tubu.

Olotu:— Hẹn oko mọ



Yẹyẹnatu:— A kọ le sọ boya ọbẹ ti ẹ nla ti jẹ ki ẹ gbagbe pe kirikiri lo njẹ tubu.

Olotu:— Isọkusọ ti o ba wun ọ o le fẹnu rẹ sọ ẹsẹ ole ni yio wọ tubu, ti emi ko ba jale ṣe nko ni wọ tubu.

Yẹyẹnatu:— O dara ẹ ma binu Nwọn ni ara nyin ko ya ni mo ṣe ni ki nwa wo yin.

Olotu:— O yẹs. o tẹ mi diẹ ni

Yẹyẹnatu:— So Iyawo yin?

Olotu:— Ni kini?

Yẹyẹnatu:— Lo tẹ yin?

Olotu:— Ṣe o de? Mo ni ara mi ko ya diẹ ni.

Yẹyẹnatu:— O. sọri pupọ.

Olotu:— Ha! ha! o ma ti nsọyinbo rẹpẹtẹ nisisiyi kẹ.

Yẹyẹnatu:— Ofin ni yẹn.

Olotu:— Lotọ ni sa, nitori o ti nwọ aṣọ Oyinbo

Yẹyẹnatu:— Emi, ẹ si ti ri ẹniti ko le rowo raṣọ rara ni yẹn.

Olotu:— Hẹ! tani sọ pe o ko rowo raṣọ nisiyi ?

Yẹyẹnatu:— Ha! ha! ẹni mo wọ aṣọ oyinbo. O dara, ẹ daruko oyinbo ti mo wọṣọ rẹ?

Olotu:— Yẹyẹnatu, tilẹ jẹ kori rẹ pe. A ni o ti nwọṣọ ti oyinbo ṣe nisisiyi.

Yẹyẹnatu:— Tẹlẹtẹlẹ nkọ, iyẹn ni pe ki iṣọ oyinbo lo ṣaṣọ nailọnu ti mo nwọ?

Olotu:— Iyẹn ni pe o nwọ kaba tẹlẹ?

Yẹyẹnatu:— Hun-hun, ṣe o tan? Ẹ tun sọrọ ko ye enia ti. O ma ṣe o Boya ara nyin ko ti ya ni. Kini o nṣe yin gan papa?

Olotu:— Maleriya ni, nwọn si ni o kari ilu.

Yẹyẹnatu:- Ha! abajọ o nṣe Adija, Suberu, Ramọnu, Sunmọnu, Nahun, Sulemọnu, ati Mẹmunọ.

Olotu:- Imale ni kan kọ lo nṣe kẹ.

Yẹyẹnatu:— Maleri ya ko gbọdọ se Igbagbọ kẹ.

Olotu:- Ha! o ko mọ ikan Ko si ẹniti ko le ṣe.

Yẹyẹnatu: Tabi ki iṣe Imale ri iya lẹ po ni? Ṣe bi ki iṣe Igbagbọ ri iya.

Olotu:- Gbẹnu rẹ sọwọn.

Yẹyẹnatu:- Ẹ tek riski kẹ.

Olotu:- Sa ma lọ

Yẹyẹnatu:- Hẹn! ko buru, o dabọ.

## Ọgbẹni Denis Parker yio fiṣẹ silẹ

Ọgbẹni D. H. L. Parker ti iṣe Alabojuto ile-iṣẹ Irohin U. A. C. l'Eko ti sọ ifẹ rẹ lati lọ si ile fun isinmi-ifẹhinti lẹnu iṣẹ ni Naijiria ni ipari ibọwọ rẹ.

Yio si lọ si Ilu Ọba ninu oṣu ti mbọ yi.

Ni ọdun 1957 ni Ọgbẹni Parker di Alabojuto Irohin U. A. C. l'Eko lẹhin ti o ti ṣe iṣẹ yi ni Ipinlẹ-Ariwa. O di gba o.

## IWE SI OLOTU

### Ẹ LA EYI YEMI ?

Olotu/

Jọwọ gba mi laye lati ṣe ibere yi lọdọ awọn ọnkawe wa ati paapa julọ awọn onimọ ijinlẹ ninu ọrọ Ọlọrun.

Ibere na ni pe, Iwe Mimọ sọ wipe, ko si ẹṣẹ ninu ohun ti a jẹ lati ẹnu si inu wa, ṣugbọn eyi ti o ba ti ẹnu jade ni sọ ni di alaimọ ati ẹlẹṣẹ.

Alhaji kan si sọ wipe a ko gbọdọ jẹ ẹlẹdẹ.

Ewo ni ki a gbagbọ ninu mejeji Alhaji tabi Bibeli Mimọ Ọlọrun?

Abọ mi re o.

Emi ni
M. A. POPOỌLA

SHOMOLU

### OTITỌ NI YIO LEKE

Olotu/

Yio dun mọ mi ninu pupọ ti o ba le gba mi laye ninu iwe rẹ oloyin mọmọ lati kede ohun ti o ya mi lẹnu lọjọ Sunday ti o koja tiṣe ọjọ kejilelogun oṣu yi.

Mo ki gbogbo ẹnyin ti ẹ fi iṣẹ yin silẹ ni ọjọ na bi o tilẹ jẹ wipe ọjọ Isinmi ni ọjọ na jẹ sibẹ sibẹ ẹ ti ori nyin bọ ojo lati lọ pade Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ, Oluwa yio bu kun Olukuluku yin, Oluwa atl ilu wa na ti o kun fun Wara ati Oyin yio wa ninu aiye tiyin na awọn ibi aiye ko ni ri yin gbeṣe ajinde ara yio ma jẹ fun nyin, paapa ẹnyin ti ẹ jẹ ojulowo ọmọ Yoruba ti ẹ tun fi asiko Isinmi yin silẹ ti ẹ tẹlẹ Aṣiwaju rere.

Lai ṣeaniani inu mi dun gidigidi pe ẹ mọ otitọ yatọ si irọ pipa, emi ko sọ pe ki a sope enia kan jẹbi tabi ẹnikan jare bikoṣepe orilẹ-ede wa Iwọ Orun ti nwọn fẹ gbe ta fun awọn Alaimọ ti nwọn ko mọ ọtun yatọ si osi.

Nitori idi eyi adura mi ni pe ki ẹ jẹki a ran otitọ lọwọ ki a le gunlẹ si ebute rere.

Emi ni
AFUSATU LAYẸNI

EKO

### Ẹ LA EYI YEMI ?

Olotu/

Jọwọ gba mi laye lati ṣe ibere mi yi lọwọ awọn ọnkawe Irohin Imọlẹ, mo fẹ mọ ẹniti o jọbi ninu awọn mẹtẹta yi.

Ẹniti o fi magun le iyawọ rẹ, tabi iyawo ti ọkunrin ọlọkunrin lu magun ni ara rẹ tabi ẹniti o ṣe ogun magun fun ọkọ Iyawo?

Olotu, mo dupẹ aye ti ẹ gba mi o,

Emi ni
LATIFU BABALỌLA

EKO

### Ẹ LA EYI YEMI ?

Olotu/

Jọwọ gba mi laye lati ṣe ibere meji mi yi lọwọ awọn Ọjọgbọn ọkawe Irohin Imọlẹ akọniọlọgbọn ti o kun fun ọpọlọpọ ẹkọ ati ọrọ lakaye. Awọn Agbalagba a ṣa ma sọ pe "Bere-bere ki iṣi bere" Ibere na niyi:-

1. Kini ṣe ti awọn enia fi ma nsọ wipe Ọkọ ni oriṣa Obinrin? (2) Obinrin koṣe ma ni, ti a ba si ni tan iyọnu ni?

Ngo ma reti esi nyin o.

Emi ni
SAKA A. OLOWONILARA

EBUTE MẸTTA

## IFẸ LOJU (Apa kẹrindilogun)

LATI OWO:— AFỌLABI ỌLABIMTAN

Ni gbogbo ọjọ ile-iwe Iyabọ, ko wa ni ipo keji ri, ẹbun rẹ lọdọdun ko ni ye, gbogbo Oluko ni o si fẹran rẹ. Nipa iwa Iyabọ pẹlu iwe mimọ rẹ o di Ilumọka, bi o si ti jẹ pe o jẹ ọmọ kan ti o ni Itẹriba fun ẹni gbogbo ti o si tun ni Ọyaya, ọpọlọpọ bẹrẹsi sọ pe aṣẹwo ni Iyabọ iṣe.

Pupọ ninu wọn si ro pe nipa eyi ni awọn Oluko ṣe nje ki o ma wa ni ipo kini, ṣugbọn Iyabọ funrarẹ ngbọ ninu awọn ọrọ wonyi, ọpọlọpọ igba ni eto ma si nlọ ba Iya rẹ ti nwọn nsọ fun pe "O jẹ pe Iyabọ ki o ba sọrọ ki o sọ eyiti o ba fẹ ṣe, bi Ọkọ la ba fẹ fẹ ni, bi o si ṣe Iwe lo fẹ ko"

Ni igbakigba ti Muti ba gbọ ọrọ yi, inu rẹ aru, a si pe Iyabọ si kọrọ a ba sọrọ buruku, ọmọ rẹ a si ma sọkun. Nigbati o pẹ, ko ba sọrọ mọ, o fi silẹ o ni "Bi o ba ṣe wu ọ ṣe aiye rẹ, o su mi"

Gbogbo ohun ti o nṣẹlẹ yi tan nfun Iyabọ ni agbara ati ka iwe rẹ ju bi o ṣe nka lo, nitoripe o fẹ fihan ninu idanwo aṣejade ti o nti Ilu Oyinbo wa pe ọgbọn ori on ni on nlo.

Nitotọ ni akoko yi ki iṣe pe Iyabọ ko ni ọmọdekunrin ẹlẹgbẹ rẹ ti nwọn jọ nṣere ọmọde, ṣugbọn awọn mejeji ko ri aye iranu to bi gbogbo aiye ṣe nkigbe. Nigbati o si ku ọdun meji ki Iyabọ jade ni nwọn pe Lanre ni ibi iṣẹ, ti nwọn si ran lọ si ilu Oba fun ọdun meji, ọkan awọn mejeji si balẹ pe lẹhin ọdun meji nigbati awọn ba ti pari ẹkọ wọn, awọn yio tun pade.

Ki Lanre to kuro ni nwọn ti nba Iyabọ jẹ kiri, ni igba miran on na fẹ gbagbọ, ṣugbọn Ifẹ ti awọn mejejeji ni si ara won po to bẹ ti o fi jẹ wipe bi o ba ti ri oju rẹ, ọkan rẹ a yi. Nigbati o de ilu Oyinbo awọn madaru lara ọrẹ rẹ bẹrẹsi fun ni irohin buruku nipa Iyabọ gbogbo ohun ti o ṣe ati eyiti ko ṣe ni nwọn si nro mọ lẹsẹ.

Ni ikẹhin Lanre fẹ gba wọn gbọ, se ko tun ri oju Iyabọ mọ ko kọ iwe si Iyabọ mọ dede, o nsọ fun pe iṣẹ npọ. Iyabọ ti ko si mọ ohun ti o nṣẹlẹ ngbagbọ, o si nṣe otitọ lọ pẹlu rẹ gẹgẹbi ti atẹhin wa.

Nje Iyabọ bikita fun Ọkunrin miran ni ilu? Iru Ọkunrin wo ni o ngbiyanju ki Iyabọ le fẹ? Kini Iyabọ wi fun Ọkunrin na? Ki o to le dahun awọn ibere wonyi ayafi ki o ra Irohin Imọlẹ ti ọsẹ ti mbọ, maṣe salai ma kaa ni ọsọsẹ nitori Itan yi sọ nde ibiti o dun pupọ.

## Awọn Oluko ilẹ Naijiria nki ọmọ-Ọba ilẹ Gẹẹsi



Nigbati awọn ti o nko iṣẹ Oluko ni ilẹ Naijiria de ilu Oyinbo, nwọn ṣe alabapade ọmọ-Ọba Gẹẹsi ti nwọn npe ni Margaret. Inu ọmọ Ọba na si dun lati wa ki wọn.

Ẹniti o nrẹrin ti o si duro lẹgbẹ ẹniti o wọ aṣọ funfun ni a npe orukọ rẹ ni A. Ominijo, on ni ọmọ-Ọba na si mba jẹwọ.

# *ẸGBẸ IMỌLẸ AIYE*

## Ayọ ayọju ko dara

LATI ỌWỌ— ICHN OGUNSINE
No. 369, Ọmọ Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye

## A. B. D. OLOWE

LATI ỌWỌ— ADEKUNLE ADEMIJI
No. 182, Ọmọ Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye

## Ẹ KU OWURỌ O! ẸNYIN ỌMỌDE

EKO. LATIFU BAPALOLA

## Ọmọde yi ti igba ewe rẹ ya omiran Alagbara!



## FEYI KỌGBỌN

LATI ỌWỌ— SAIDU OLUPO (ILA-ARODO)
No. 357, Ọmọ Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye

Ẹ MA A KA IWE IROHIN IMỌLẸ FUN ITAN ALADUN



# YẸ IRAWỌ RẸ WO

AQUARIUS (Jan 20 – Feb 18). Iwọ yio ba ẹnikan ṣe Ipade Alayọ kan ayọ ni Opin Ipade na yio jẹ.

PISCES (Feb 19 – Mar 20). Are yio de si ọ fun gba diẹ, nkan ti o si ofẹ yi o tẹ ọ lọwọ nigbẹhin.

ARIES (Mar 21 – Apl 19). Ṣora rẹ ninu ọsẹ yi, maṣe ba ẹnikankan du Obinrin fẹ.

TAURUS (Apl 20 – May 20). Mura lati ma ṣe itọju ara rẹ ni ojojumọ ninu ọsẹ yi.

GEMINI (May 21 – Jun 20). Mura lati lo Ọgbọn ori ninu ọro kan, ti yio jẹ tirẹ nikan.

CANCER (June 21 – July 20) Maṣe fi owurọ sere bi o ba ni iṣẹ pataki lati ṣe, tete ṣe e nigba owurọ.

LEO (July 21 – Aug 22). Ori re mbẹ fun ọ lọnakọna Iwọ yio si pade alagbara kan ti yio ṣore fun ọ.

VIRGO (Aug 23 – Sept 22). Iwọ yio gbọ Ironin rere kan, ti yio mu ọ maa jọ igbadun larin awọn ọrẹ.

LIBRA (Sept 23–Oct 22) Akoko yi dara lati yanju ija ti o wa larin Ẹbi.

SCORPIO (Oct 23–Nov 21) Maṣe jẹ ki arẹ mu ọ, Nitori ohun kan yio ni iyanju. Irẹpọ mbẹ fun ọ ni ọsẹ yi.

SAGITTARUS (Nov 22–Dec 21) Maṣe ṣagidi si ọrọ ti awọn ọrẹ rẹ ba fi lọ ọ ninu ọsẹ yi, ki o si gba imọran wọn.

CAPRICORN (Dec 22–Jan 19) Ohun kan yio ya ọ lẹnu nitori ọrọ Ẹbi, maṣe da si ọrọ ti o ko mọdi rẹ rara.

---

# Ha! ẹnyin ọmọ Oduduwa Eti nyin melo?

Lati Ọwọ:- "AJẸGBORO—DAGBA"

Ajẹgboro-dagba nki nyin o, o ni alafia kọ ni ẹ wa bi? Ẹ ko ni mọ iṣoro ile Aiye, ẹni elẹni ko ni gba iṣe nyin ṣe o. Aṣe.

Gbogbo ọrọ mi a ma a dabi ase tabi apara loju awọn ẹlomiran, ṣugbọn awọn ẹniti o ba nfi ara balẹ ka ọrọ mi, yio mọ daju pe otitọ ọrọ ni mo nsọ.

Iwasu mi oni, di ori ko dori, o di ori awa ọmọ Karọ-o-jiire, mo pe gbogbo ẹnyin ọmọ Oduduwa nile loko, ki ẹ jẹ ki a parapọ, ki a duro ṣinṣin, ki a ma ṣe jẹ ki Ipinlẹ Iwọ-Orun bọ lọwọ wa, mo ro pe nisisiyi otitọ nfi oju han si gbogbo wa nipa ọgbọn ati ọna ti awọn Ọta wa ngba lati fi gba Ipinlẹ Iwọ-Orun ti o jẹ ajogun fun gbogbo ọmọ Oduduwa lọwọ wa ati pe awọn ọmọ wa ni nwọn si tun nran si we lati le ma ṣe eto na. Ẹo ri pe 'ẹhin-kule ni Ọta wa ile ni Aṣeni ngbe'. Mo si fẹ ki ẹ ṣe iranti wipe Akukọ gbangba ni o gbe ogbe ori rẹ fun Kọlọkọlọ yọ wo ni ọjọ kini.

L'ode to ni, ko si Ipinlẹ ti o tun ku nilẹ Naijiria ti awa Yoruba gbe ọkan le ti o ju Ipinlẹ Iwọ-Orun lọ Nitorina mo bẹ gbogbo ẹnyin ọmọ ibilẹ Yoruba ki ẹ maṣe jẹki Ipinlẹ yi ko kuro lọwọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre o, ẹ jẹki gbogbo wa parapo ki a ba awọn ọta wa ja. Nitori bi Ipinlẹ yi ba lọ bọ titi lailai ni ao ma jiya rẹ, titi dori aromọdọmọ wa pẹlu. Ki Oluwa maṣe fiya jẹ wa o. Ẹ maṣe jẹki a tori owo gbe ilẹ wa ta fun awọn Ọta o.

Ẹnyin Agbalagba, ẹ ba wa mu oju to ọrọ yi, o di ọwọ nyin o, Agba ki wa lọja ki ori ọmọ titun o wọ, ẹ maṣe gbọ irọ ti awọn ẹgbẹ titun kan ti nwọn lọ sodi pọ mọ awọn Ọta wa nwi fun nyin, nwọn fẹ ta ilẹ wa ti o nsan fun Wara ati Oyin ni o.

Ẹ jẹki a kun fun akanṣe adura pe ki Olorun Ọba to laiye ati Ọrun maṣe jẹki Ipinlẹ na ko bọ lọwọ wa.

Nitorina o di ọwọ gbogbo wa o. Ẹ ran awọn asiwaju wa lọwọ nipa ki ẹ fun nwọn ni ibo nyin.


# Announcement

The NIGERIAN PORTS AUTHORITY has pleasure in announcing that arrangements have been concluded for a Northern Representative (Mallam Abudullahi Obadaki) to be permanently domiciled in KANO in an office to be shortly opened in the new building of Northern Region Marketing Board, Post Office Road, Kano.

A further announcement will be made as soon as a definite opening date has been fixed.

*BAYO KEHINDE*
*Secretary to the Authority*

N. P. A. Notice No. 733
25th July, 1962.



BERE OJULOWO EGBOGI AWỌN FARANSE TI WỌN NPE NI:—

## RICHALET

FUN ARUN ẸJẸ ARA ENIA GBOGBO




Eleyi yatọ patapata si awọn Rọbi-rọbi Iṣẹ rẹ lara enia o si daju fun Iwosan gbogbo Kokoro buburu ti o ba wa ninu "ẸJẸ ARA" bi Mọnọmọnọ.

Meji rẹ kosi ninu gbogbo awọn Egbogi ti wọn npe n TỌNIKI Ẹjẹ ti wọn si nta kakiri ni owo pọọku, adimọwọ tab ki o lọ nilẹ ko di owo. Iyẹn ṣe ewọ awa ki ta awọn egbogi ba wọn yẹn rara tabi ti nwọn npota ni Ilẹ y.

Gẹgẹbi awọr Onibara wa ti mọ rufẹ awọn gbogi ba wọnyẹn nama ba ojulowo egbogi atata ti aranṣẹ fun tita lati awọn ilu Jaman, Faranse, ati ti awọn Tatambulu si Itali jẹ mọ daju pe bi ẹjẹ ara ko ba mọ daradara awọn amodi tabi ailera wọnyi le ṣe ọ. Lakuregbe, oriṣriṣi Inarun, Ojuṣuṣu tabi didun, Jẹdijẹdi Akọ-Iba, arun-Ẹdọki, Aya didun Tanpara ati Ekuru laya

Ara rro, Lapalapa, Ẹgbo-Ẹsẹ AmodbApo Ile itọ, ẹhin didun tabi Ibaradi riro pẹlu. Egbogi Risalẹt a ma pa gbogbo kokoro buruku to wa ninu ẹjẹ ara patapata yio si fọ ẹjẹ rẹ mọ tontoni pẹlu. Ṣa dan Igo rẹ kan wo lara rẹ dajudaju wọ yio ma rohin rẹ fun ẹlomiran pẹlu nigbakugba.

ADEDUN CHEMISTS,
WAKEMAN STREET, YABA.

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street, Lagos,**
**Phone: 22878 Nigerian, (Oja ita Fji)**

NIGERIAN MEDICINE STORES
4, TINUBU STREET, LAGOS. PHONE: 20278.

WATERLOO MEDICINE STORE
11A, FAGBEWESA STREET OSHOGBO

# EYI NI AWỌN ỌJỌ ỌJA ILẸ YORUBA

## ỌJỌ AJE JULY 30 (MONDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ . ABẸOKUTA — — — — — — | Agege, Ikeja, Ebute-Ero, Ọja-Ajido Lafenwa, Ọbada, Ọba, Kajọla, Ajegunle, Idogo |
| IBADAN — — — — — — — | Lalupọn, Ajegunle, Owode, Igbo-ọra |
| IJẸBU — — — — — — — — | Ibefun, Atikori, Imushin, Agọ-Iwoye, Ijẹsha-Ijẹbu, Isara, Imodi |
| IJẸSHA — — — — — — — | Iwara, Ejioro, Odo, Ibokun, Ijẹbu-Ijẹsha |
| ẸGBADO — — — — — — — | Lasilo, Idiẹmi |
| EKITI — — — — — — — — | Okemesi, Ifaki |

## ỌJỌ IṢẸGUN JULY 31 (TUESDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ . | Oyingbo |
| ABẸOKUTA — — — | Ijoko, Iberekodo, Asu, Wasimi |
| IBADAN | Akeroro, Idọfin, Lagun, Ṣagbẹ, Ogunjana, Mọlete |
| IJẸBU — — — — — — | Aiyepe, Ṣagamu, Itaosu, Ogere, Irolu, Itele, Ode - Rẹmọ |
| IJẸSHA — — — | Ibodi, Ibode, Kajọla, Imesi - Ile |
| ẸGBADO — — — — — | Alagba, Ilarọ, Ọja—Ọdan, Sunwa, Iboro |
| EKITI — — — — — — | Ilogbo, Ishan |

## ỌJỌ'RU AUGUST 1 (WEDNESDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ . | Ọbun - Eko |
| ABẸOKUTA — — — — | Atan, Agbado, Ifọ, Itori, Itoku, Isabọ, Ọdẹda, Ibara |
| IBADAN — — — — — | Fẹdẹgbo, Oyedeji, Ẹgbẹ-da, Babalokuta |
| IJẸBU — — — — — | Ilishan, Odogbolu, Atan, Imope, Iṣara, Imodi, Ishan |
| IJẸSHA — — — — — | Ẹpẹ, Iloba, Imuroko, Erinmọ, Ilase, Iperindo |
| ẸGBADO — — — — — | Aiyetoro, Ado - Odo |
| EKITI — — — — — — | Egosi, Odo—Aiyedun |

## ỌJỌ ỌJỌBỌ AUGUST 2 (THURSDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ILU |
|---|---|
| EKO ATI AGEGBE RẸ . | Mushin, Badagry |
| ABẸOKUTA — — — | Otta, Abalabi, Sodẹkẹ, Omida, Ilawo |
| IBADAN — — — — | Ituko, Sojukonko, Tọwọbowo, Temidire |
| IJẸBU — — — — — | Ikẹnnẹ, Ọkun-Ọwa, Erunwọn, Omu, Mamu |
| IJẸSHA — — — — — | Oshun, Itagun, Odogbo, Idoko, Iloko |
| ẸGBADO — — — — — | Igbogila, Ijoun, Imasai, Owode |
| EKITI — — — — — — | Oke—Aiyedun |

## ỌJỌ ẸTI AUGUST 3 (FRIDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ . ABẸOKUTA — — — — — | Agege, Ikeja, Lafenwa, Ọbada, Ọba, Kajọla, Ajegunle, Idogo |
| IBADAN — — — — — — | Lalupọn, Ajegunle, Owode, Igbo ọra |
| IJẸBU — — — — — — — | Ibefun, Atikori, Imushin, Agọ-Iwoye, Ijẹsha, Ijẹbu, Isara Imodi |
| IJẸSHA — — — — — — | Iwara, Ejioro, Odo, Ibokun, Ijẹbu, Ijẹsha |
| ẸGBADO — — — — — — | Lasilo, Idiẹmi |
| EKITI — — — — — — — | Okemesi, Ifaki |

## ỌJỌ ABAMẸTA AUGUST 4 (SATURDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ . | Oyingbo, Ejiorin |
| ABẸOKUTA — — — — | Ijoko, Iberekodo, Asu, Wasimi |
| IBADAN — — — — — | Akeroro, Idọfin, Lagun, Ṣagbẹ, Ogunjana, Mọlete |
| IJẸBU — — — — — — | Aiyepe, Ṣagamu, Itaosu, Ogere, Irolu, Itele, Ode - Rẹmọ |
| IJẸSHA — — — — — | Ibodi, Ibode, Kajọla, Imesi - Ile |
| ẸGBADO — — — — — | Alagba, Ilarọ, Ọja - Ọdan, Sunwa, Iboro |
| EKITI — — — — — — | Ilogbo, Ishan |

## ỌJỌ AIKU AUGUST 5 (SUNDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ . | Ọbun-Eko, Ikosi, Ẹpẹ |
| ABẸOKUTA — — — — | Atan, Agbado, Ifọ, Itori, Itoku, Isabọ, Ọdẹda, Ibara |
| IBADAN — — — — — — | Fẹdẹgbo, Oyedeji, Ogbuṛo, Ẹgbẹda, Babalokuta |
| IJẸBU — — — — — — | Ilishan, Odogbolu, Atan, Imọpe, Ishan, Isara, Imodi |
| IJẸSHA — — — — — | Ẹpẹ, Iloba, Imuroko, Erinmọ, Itase, Iperindo |
| ẸGBADO — — — — — | Aiyetoro, Ado - Odo |
| EKITI — — — — — — | Egosi, Odo - Aiyedun |

## ỌJỌ AJE AUGUST 6 (MONDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ . | Mushin |
| ABẸOKUTA — — — — | Otta, Abalabi, Sodẹkẹ, Omido, Ilawo |
| IBADAN — — — — — | Ituko, Sojukonko, Tọwọbowa, Temidire |
| IJẸBU — — — — — — | Ikẹnnẹ, Ọkun - Ọwa, Erunwọn, Omu, Mamu |
| IJẸSHA — — — — — | Oshun, Itagun, Odogbo, Idoko, Iloko |
| ẸGBADO — — — — — | Igbogila, Ijoun, Imasai, Owode |
| EKITI — — — — — — | Oke—Aiyedun |

# Adamọdi Onişegun kan wẹwọn Ọdun kan-Abọ

Ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kọkanlelogun oṣu yi ni awọn Ọlọpa mu Ọdaran kan, John Igwe awamọto ẹni ogoji ọdun wa si iwaju Adajọ Agba kotu kekere kan ni Owerri fun ẹsun pe, o mu egbogi Oyinbo dani lai gba Iwe-aṣẹ.

Alaye ti Ọlọpa ti o ba ọdaran na ṣejọ ṣe ni kọtu ni wipe. Awọn ri ọdaran na pẹlu Ogun majẹlẹ ati Abẹrẹ Oyinbo ti nwọn fi nṣe Itọju awọn alaisan, ati pe awon si hi lere pe "ni bo ni o ti ri awọn nkan ti o wa ni ọwọ rẹ" wọn ni ko le fun awọn ni esi kan. Ni awọn ba fi mu wa si kọtu

Nigbati Ọdaran na rojọ ti o si gba pe on jẹbi ni Adajọ ba fi ni ki o lọ fi ẹwọn Ọdun kan abọ jura.

Padi Ṣọọṣi Ijọ Aguda, ẹniọwọ M. Adrien ni Nsukka lọ si Ile Ifowo pamọ lati lọ parọ awọn owo atijọ ti o wa lọwọ rẹ ni Ọjọ'Ru ti iṣe ọjọ kejidinlogun oṣu yi, ni awọn Ole ba ji Ogoji pọnun (£40) mọ ọ lọwọ.

Awọn Ọlọpa si nwa awọn Ole na nisisiyi.

# Okunrin kan lugbadi Ofin

IBADAN:- Awọn Ọlọpa mu Ọdaran kan, Nathaniel Eze ẹni Ọdun mejilelogun wa siwaju Adajọ Agba Kọtu Ibadan fun ẹsun irọ-pipa

Awọn Ọlọpa ṣe alaye ni Kọtu pe Ọdaran na wa si Teşan awọn Ọlọpa ni ọjọ Eti ti iṣe ọjọ kẹtala oṣu yi o si sọ wipe awọn Ole ti fọ Ilẹkun Iyara on nwọn si ji pọnun meji (£2) to wa ninu Iyara on, Ọlọpa tun ṣe Alaye pe nigbati awọn de Ile Ọdaran ni awọn ri pe irọ lo pa fun awọn, iṣẹ Agbọnjọ ni Ọdaran na nṣe ni Ile ra, o si ngba pọnun mẹfa (£6) loṣu.

Ọdaran na gba pe on jẹbi irọ ti on pa fun awọn ọlọpa ni Adajọ ba ni ki o lọ fi pọnun mejila (£12) taran si kọtu tabi ki o lọ si ẹwọn Ọdun kan-Abọ.

# Akiyesi

ITAN FEYI KỌGBỌN YIO BERESI MAA JADE NINU "IWE IROHIN IMỌLẸ" LAIPẸYI.

Ẹ MAA FOJUSỌNA, KI Ẹ SI MAA KA IROHIN IMỌLẸ NIGBAGBO, KI O SI KỌ ỌPỌLỌPỌ ỌGBỌN TI O WA NINU ITAN NA.

ITAN NA KO ṢE ROHIN.

OLOTU

GBANGBA DEKUN KEDERE BE WO!




OLU BORI EGBOGI IKO

## THIOLYPTINE

Bi amodi "IKO" ti ojo re ti pe tabi ti o nyo o lenu fun nkan bi odun kan tabi ju be lo, awon egbogi robrobi ko le se iwosan re rara. ma fi owo re se ofo mo.

Bere fun egbogi ojulowo awon ara ilu Faranse ti nwon npe ni "THIOLYPTINE" Ojulowo haun-haun atamatase egbogi fun IKO FERE, Iko Tuto, Iko Ona-ofun, Iko Iile, Iko ti o ma nmu ki enia ma tu kelebe nigbakugba lati inu Ifun wa (LUNGS) tabi ti o ma nmu ki enia tu pelo. Bi o ba dan Igo kan egbogi Thiolyptine wo Iwo na yio ri iyato lara re ni kiakia Igba-aya tabi ona ofun re ti o ma nho yio duro "IKO" re yio si san pata-pata iwo yio si ma jeun daradara, iwo yio si ma sun fonfon pelu alafia ara.

Bere egbogi yi ati awon orisirisi egbogi Iko miran ni Sobu awon:-

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street, Lagos.**
**Phone: 22878 Nigerian, (Oja ita Faji)**

NIGERIAN MEDICINE STORES
4, TINUBU STREET, LAGOS. PHONE: 20278.

ADEDUN CHEMIST
WAKEMAN STREET, YABA. PHONE: 22878.

## Nigerian Ports Authority

INVITATION TO TENDER-ATLANTIC TERMINAL CATERING

Tenders are invited by the NIGERIAN PORTS AUTHORITY for the provision of catering facilities at the Atlantic Terminal Apapa Quays, on the days of arrival and departure of Mailboats for a period of three years commencing on 1st September, 1962.

2. Tender Documents, giving details of the Services to be provided and setting out the general conditions of the contract may be obtained from the Secretary to the Authority, Nigerian Ports Authority, 216, Broad Street, Lagos, on deposit of the sum of £5 which shall be returned by the Authority on receipt of a bona fide tender.

3. The deposit of £5 should be made to the Authority's Cashier, Accounts Department, Apapa Quays.

4. Tenders should be enclosed in sealed envelopes marked "CONFIDENTIAL - ATLANTIC TERMINAL CATERING" and forwarded to the undersigned so as to reach him not later than 4 p. m. on the 9th August, 1962.

5. The Authority is not bound to accept any tender.

*BAYO KEHINDE*
*Secretary to the Authority.*

N. P. A. Notice No. 748,
27th July, 1962.

## Nigerian Ports Authority

INVITATION TO TENDER

### SCRAPS.

Tenders are invited by the Nigerian Ports Authority for the purchase of Scrap materials now lying at the Authority's premises at Port Harcourt.

2. A copy of the tender form may be obtained from the Secretary to the Authority, 216, Broad Street, Lagos, or Port Manager Eastern Ports, Nigerian Ports Authority, Port Harcourt, on payment of a deposit of £5 (five pounds) to the Authority's Cashier, Accounts Department, Apapa Quays, or to the Area Accountant, Nigerian Ports Authority, Port Harcourt. The completed tender form should thereafter be addressed to the Secretary to the Authority in a sealed envelope marked "CONFIDENTIAL-TENDER FOR SCRAP MATERIALS" so as to reach him not later than 11th August 1962.

3. The successful tenderer will be required to remove the Scrap at his own expense within 7 days of the acceptance of his offer. The deposit of £5 (Five pounds) will not be refounded in any event to any tenderer who, upon being advised of the acceptance of his tender fails to pay for and remove the Scrap. He will also be required to make necessary arrangments at his expense for the Scrap to be weighed in the presence of a representative of the Authority before being removed.

4. Tenderers are warned that Scrap available for disposal may comprise both ferrous and non-ferrous materials, although it is expected that most of the materials will be ferrous.

5. The Authority do not bind themselves to accept the highest or any tender.

*BAYO KEHINDE*
*Secretary to the Authority.*

N. P. A. Notice No. 732.
23rd July, 1962.

BERE EGBOGI PATAKI YI TI WON NPE NI:-

# "Figurana"

Je ojulowo egbogi ti awon Jamani sese se iwadi re fun awon ti o ba sanra tabi ti o ba "TOBI" ju lati ma mu ki won le fon tabi jonku lai si wipe won ma ka ewo onje ti nwon o ma je rara be si ni ko lewu ni lilo fun enia rara.

Ki enia sanra, gborin, tabi ki o tobi pupoju ki nse ohun ti o dara rara, opolopo amodi ni o nko ba enia, bi Lakuregbe, Aikole gbera ni ile bi o ba joko Aya lilu kiki tabi jija nigbakugba aikole ni konle daradara, ara wiwo tabi wiwuwo, Eemi mimi ho-ho ati orisirisi amodi omiran pelu.

Sa dan Igo re kan wo, Iwo na yio ri ayipada ati Alafia ti yio de si o. Bere ni Sobu awon Olori elegbogi Jamani ni igboro ilu Eko:-

ADEDUN CHEMISTS,
WAKEMAN STREET, YABA.

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street, Lagos.**
**Phone: 22878 Nigerian. (Oja ita Fji)**

NIGERIAN MEDICINE STORES
4, TINUBU STREET, LAGOS. PHONE: 20278.

WATERLOO MEDICINE STORE
11A, FAGBEWESA STREET OSHOGBO

*Printed and Published by MODUPE PRINTING PRESS 16, Bamgbose Street. P. O. Box 1495, Phone 21985, Lagos. Olotu:- E. A. Adeniji, 24, Oliyide Street, Odo-Abore Mushin.*